ACALAN- AU

# COVID-19

# Yoruba

## Kín ni Àrùn Ọ̀ṣọ́ Abọ́dún-2019-dé?

Àrùn Ọṣọ́ Abọ́dún-2019-dé jẹ́ àrùn tó ń ràn láti ara ẹnìkan sí ẹlòmíràn tí ó tipasẹ̀ Kòrónà fáírọ́ọ̀sì tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ sàwárí wáyé ní kòpẹ́kòpẹ́ yìí. Fáírọ́ọ̀sì tuntun àti àrùn yìí ni wọ́n jẹ́ ohun àìmọ̀ tẹ́lẹ̀ títí di àkókò tí ó bẹ́ sílẹ̀ ní Wuhan ní orílẹ̀èdè China ní oṣù kejìlá ọdún 2019.

## Kí ni Àwọn Àmì Ìtọ́kasí Àrùn Ọṣọ́ Abọ́dún-2019-dé?

i. Àwọn àmì ìtọ́kasí àrùn ọṣọ́ abọ́dún-2019-dé ní pàtàkì jù lọ ni ibà, àárẹ̀ ara àti ikọ́ ẹ̀gbẹ. Àwọn aláìsàn mìíràn máa ń ní ẹ̀fọ́rí àti ara ríro, imú dídí, yíyọ ikun nímú, ọ̀nà ọ̀fun dídùn tàbí ìgbẹ́ gbuuru. Àwọn àmì ìtọ́kasí yìí sáábà máa ń farahàn wẹ́rẹ́wẹ́rẹ́ tàbí kí wọ́n rọra fẹ̀sọ̀ bẹ̀rẹ̀.

ii. Àwọn ènìyàn mìíràn á ti kó àrùn yìí ṣùgbọ́n àwọn àmì ìtọ́kasí kan kìí gbèrú lára wọn, bẹ́ẹ̀ n wọn kìí ká gúọ́gúọ́. Ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ènìyàn (bí ìdá ọgọ́rin nínú ọgọ́rùn-ún/ìdá mẹ́jọ nínú mẹ́wàá) ni wọ́n máa ń borí àìsàn yìí láì jẹ́ pé wọ́n gba àkànṣe ìtọ́jú. Ọ̀kan láàrin àwọn ẹlénìyàn mẹ́fà tí wọ́n kó àrùn ọṣọ́ abọ́dún-2019-dé ni wọ́n máa ń padà ṣe àìsàn ńlá, tí wọn á sì ní ìṣòro èémí mímí.

iii. Àwọn àgbàlagbà àti àwọn ẹlòmíràn tí wọ́n ti ní ìṣòro àìsàn abẹ́nú bí ẹ̀jẹ̀ ríru, àìsàn ọkàn tàbí ìtọ̀ ṣúgà ní ewu sáábà máa ń wu débi pé wọ́n a pilẹ̀ àìsàn ńlá. Àwọn ènìyàn tí ó bá ní ibà, ikọ́ àti ìṣòro nípa èémí mímí gbọdọ̀ wá dókítà lọ.

ACALAN
African Academy of Languages
AFRICAN UNION

## Ǹjẹ́ a ti ní abẹ́rẹ́ àjẹsára, oògùn tàbí ìtọ́jú fún àrùn ọṣọ́ abọ́dún-2019-dé?

i. Lọ́wọ́lọ́wọ́ báyìí, kò tíì sí àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára tàbí ìtọ́jú fún àrùn ọṣọ́ abọ́dún-2019-dé. Àmọ́, aáyan ti ń lọ níbùdó ìtọ́jú níbi tí wọ́n ti ń ṣe ìgbéléwọ̀n àwọn ohun tó ṣeé ṣe gẹ́gẹ́ bí ìtọ́jú. Àjọ Elétò Ìlera Àgbáyé (World Health Organisation - WHO) kò ní káàárẹ̀ láti máa ṣe ètò ìtanilólobó lórí àdédúró ipò àìsàn yìí nígbàkúùgbà tí wọ́n bá ṣe àwárí ohun ọ̀tun ní ibùdó ìtọ́jú.

## Àbùdá Àmì Ìtọ́kasí Kòrónà Fáírọ́ọ̀sì (Àrùn Ọṣọ́ Abọ́dún-2019-dé)

- Ikọ́,
- Ibà,
- Àárẹ̀ ara,
- Imú dídí,
- Ṣíṣe ikun-nímú téré téré,
- Ọfun dídùn tàbí ìgbé gbuuru,
- Ìdíwọ́ nípa mímí.

ACALAN
African Academy of Languages
AFRICAN UNION

## Ìtànkálẹ̀ Kòrónà Fáírọ́ọ̀sì (Àrùn Ọṣọ́ Abọ́dún-2019-dé)



- Yàgò pátápátaá tàbí dín ìfarora làwùjọ kù,
- (Yẹra) fún fífọwọ́ kan àwọn nǹkan àti òke pèpéle, kí o má ba à tipa bẹ́ẹ̀ fọwọ́ kan ojú, ẹnu, imú àti àwọn ẹyinjú kí o tó fọ ọwọ́ rẹ.

ACALAN
African Academy of Languages
AFRICAN UNION

# ÀWỌN ÌGBÉSẸ̀ KÀŃPÁ FÚN ÌDÁÀBÒ-BÒ LỌ́WỌ́ ÀJÀKÁLẸ̀ ÀRÙN KÒRÓNÀ FÁÍRỌ́Ọ̀SÌ (ÀRÙN ỌṢỌ́ ABỌ́DÚN-2019-DÉ)



### Fọ ọwọ́ rẹ lemọ́lemọ́

Ní gbogbo ìgbà fọ ọwọ́ rẹ dáadáa pẹ̀lú tẹ̀ẹ́pọ̀rọ̀¸tí a fi ọtí líle pilẹ̀ rẹ̀ fún ọwọ rírа tàbí kí o fọ ọwọ́ rẹ̀ pẹ̀lú ọṣẹ àti omi.




### Pa ìlànà ìtakété sí ara ẹni mọ́

Fi ààyè ìtakété, ní déédé mítà kan (ẹsẹ̀ bàtà mẹ́ta) sílẹ̀, láàrin ara rẹ àti ẹnikẹ́ni tí ó ń húkọ́ tàbí sín.



### Yẹra fún à ń fọwọ́ kan ojú, imú àti ẹnu

Ọwọ́ máa ń kan orísìírísìí òkè ìpépéle, nípa bẹ́ẹ̀ wọn á kó fáírọ́ọ̀sì. Tí wọ́n bá ti kárùn báyìí, ọwọ́ á tipa bẹ́ẹ̀ taari àwọn fáírọ́ọ̀sì sí ojú, imú tàbí ẹnu. Láti ibẹ̀, fáírọ́ọ̀sì lè ṣe bẹ́ẹ̀ wọnú àgọ́ ara rẹ, o sì lè ti ipasẹ̀ bẹ́ẹ̀ di aláìsàn.




### Wà nínú ilé rẹ ti ara rẹ bá ń lọ́ tìkọ̀tìkọ̀

Tí o bá ní ibà, ikọ́ àti ìdíwọ́ nípa mímí, kàn sí Dókítà, sì rí i pé o pè é ṣaájú lílọ rẹ.




### Húkọ́ tàbí sín sí ibi tí aṣọ bò lápá rẹ

- Bo ẹnu àti imú nígbà tí ó bá ń húkọ́ tàbí sín,
- Lo tóílẹ̀tíroò tàbí aṣọ ìgúnpá ọwọ́ má lo ọwọ́ lásán.

Orísun: Àjọ Elétò Ìlera Àgbáye